# FIFI JOSẸFU SINU TUBU LAI TỌ́

**Gẹnẹsisi 39:1-6, 19-23;  1 Peteru 2:18-24**

**ẸKỌ  34  ---  FUN  AGBA**

**AKỌSORI:   "Nitori ogo kili o jẹ, nigbati ẹ ba ṣẹ̀ ti a si lù nyin, bi ẹ ba fi sũru gbà a? ṣugbọn nigbati ẹnyin ba nṣe rere; ti ẹ si njiya, bi ẹnyin ba fi sũru gbà a, eyi ni itẹwọgbà lọdọ Ọlọrun" (1 Peteru 2:20).**

**I  Igbega ati Iṣẹ Iriju Otitọ ti Josẹfu**

1 A mu Josẹfu lọ si agbegbe titun, ẹrú ni ile Pọtifari, Gẹnẹsisi 39:1, 2;  45:8

2 O jẹ́ olotitọ si Ọlọrun sibẹ, Ọlọrun si pada san án fun un pẹlu ọpọlọpọ ọrọ̀ ati ibukun, Gẹnẹsisi 39:2, 3;  Orin Dafidi 1:1-3

3 Pọtifari gbé e si ipò giga, Ọlọrun si bukun fun Pọtifari nitori ti Josẹfu, Gẹnẹsisi 39:4, 5;  12:3;  Owe 16:7

4 Josẹfu fi ara rẹ̀ hàn bi oloootọ iriju, Gẹnẹsisi 39:6;  1 Kọrinti 4:2

**II  Idanwo Josẹfu ati Fifi Sinu Tubu Lai Tọ́**

1 Iyawo Pọtifari sun Josẹfu ni ẹ̀sun èké, Gẹnẹsisi 39:19; 1 Peteru 4:4, 5

2 Pọtifari paṣẹ pe ki a fi Josẹfu sinu tubu lai wadii ododo ọ̀rọ naa daju, Gẹnẹsisi 39:20;  Orin Dafidi 105:17-19

3 Ọlọrun wà nitosi lakoko ipọnju ati iyiiriwo rẹ̀, Gẹnẹsisi 39:21;  Orin Dafidi 34:19;  Isaiah 43:2;  1 Kọrinti 10:13

4 Josẹfu jẹ́ oloootọ iriju sibẹ, paapaa nigba ti o wà ninu tubu, Gẹnẹsisi 39:21-23;  1 Peteru 2:18-24;  Romu 12:17, 18

## ALAYE

A ri Josẹfu nisisiyii laaarin ibi ti o yatọ patapata si ti igba èwe rẹ̀.  Baba rẹ̀ ni ọrọ̀ pupọ ni ti agbo-ẹran maluu ati agutan; ṣugbọn nipa iriri titun ni ile Pọtifari ni Egipti, ọdọmọkunrin yii mọ ohun ti i ṣe ojulowo ọ̀ṣọ́ ati ẹwà igbadun ayé laaarin ilu ajeji yii.  Awọn arakunrin rẹ̀ tà á si oko-ẹrú; ṣugbọn a ri i pe ipò irẹwẹsi bayii paapaa kò mú ki o kọ Ọlọrun baba rẹ̀ ati ti awọn baba-nla rẹ̀ silẹ.  Nigba èwe rẹ̀, o jẹ́ ọmọ oloootọ́, ti o yege laaarin apẹẹrẹ buburu ati iwakiwa awọn arakunrin rẹ̀; ṣugbọn nisisiyii a o dán iwa rere rẹ̀ wò ju ti atẹyin wá lọ.  Laaarin gbogbo rẹ̀, o fi agbara Ọlọrun ti n pa ni mọ́ ni igba iṣoro gbogbo hàn, ati nitori iwa otitọ rẹ̀, o di apẹẹrẹ rere fun gbogbo eniyan kaakiri agbaye ni gbogbo igba.

Nigba ti Ọlọrun kọkọ pe Abrahamu, O ṣeleri ibukun ti o tobi jù lọ ninu ohun ti Ọrun ati ayé fun eniyan Ọlọrun yii, ati fun irú ọmọ rẹ̀ lẹyin rẹ̀.  Nihin ni a ri apẹẹrẹ imuṣẹ ileri Rẹ̀: "Emi o bukun fun awọn ti nsúre fun ọ."  Josẹfu di aayo ọmọ-ọdọ ijoye ara Egipti naa; Ọlọrun bu ọlá fun ileri Rẹ̀ nipa bibukun Pọtifari, nitori Josẹfu.  Ọlọrun kò gbagbe majẹmu Rẹ̀.  Oun kò fi awọn ileri Rẹ̀ jafara.  A le "mu ibeere wa" wá lori ọkọọkan awọn ileri wọnyii, ki a si gbẹkẹle wọn ninu iṣoro-kiṣoro ti o wù ki o doju kọ wá ninu ayé.

Ẹlẹṣẹ le sọ bi ẹni kan ba n sin Ọlọrun ni tootọ tabi kò sin In.  Ọga Josẹfu ri i pe Ọlọrun wà pẹlu rẹ̀.  O sin oluwa rẹ̀ pẹlu otitọ ọkàn ati gbogbo agbara rẹ̀, o si fi hàn pe oun jẹ́ ẹni ti a le gbẹkẹle ninu ohun gbogbo.

Ẹkọ nla wà fun wa nihin.  Nigba ti ẹni kan bá gbà wá si iṣẹ́, a gbọdọ jẹ ki o mọ̀ pe awa ni ẹni ti o ṣe e gbẹkẹle ju lọ ni ibi iṣẹ rẹ̀, nipa iwa otitọ ati akinkanju wa.  Lọna bayii oun yoo ri iyipada nla ti Ọlọrun ti ṣe ni igbesi-ayé wa, yoo si mọ agbara iyanu ti ó wà ninu Ihinrere Kristi.

Imọ Ọlọrun otitọ diẹ wà ni Egipti, bi o tilẹ jẹ pe a ko dá isin Rẹ̀ silẹ nibẹ bẹẹ ni a kò si gba a layè.  Boya igbesi-ayé ẹni iwa-bi-Ọlọrun Abrahamu ni o ṣe eyi, ẹni ti o ti ṣe atipo ni ilẹ abọriṣa yii rí.  Pọtifari ni imọ Ọlọrun diẹ, nitori o mọ̀ ni tootọ pe Oluwa wà pẹlu Josẹfu.

Bawo ni a ṣe ni lati ṣọra tó bi a ti n gbé aarin awọn alaiwa-bi-Ọlọrun!  Nibikibi ti a bá n lọ, ẹni kan n ṣọ́ wa lati ri boya igbesi-ayé wa ba igbagbọ́ ti a jẹwọ pe a ni mu.  Kò si ibi ti iduro igbagbọ́ wa ko ni di mimọ̀, bi a ba ni isopọ ni tootọ pẹlu Ọlọrun ati Ọrun, kò si si ibi ti imọlẹ wa ko ti ni mọlẹ ninu okunkun, bi Imọlẹ ayé ba wà ninu ọkàn wa.  Josẹfu jẹ́ oloootọ ọmọ-ọdọ si Ọlọrun rẹ̀, nibikibi ti o wù ki o wà -- ni oko pẹlu awọn arakunrin rẹ̀, ni ile Pọtifari gẹgẹ bi ọmọ-ọdọ tabi iriju ninu tubu labẹ idajọ ti ko tọ́, tabi lori itẹ gẹgẹ bi alaṣẹ Egipti.

Nigba ti ayé ba n yẹ wa, ti o si dabi ẹni pe gbogbo nnkan n lọ deedee, a gbọdọ ṣọra gidigidi ki ọ̀tá wa ẹmi má baa dẹkùn mu wa.  Idanwo yoo de bá olukuluku wa.  Nipa wọn ni a fi n mọ iwa otitọ ati ifẹ wa si Ọlọrun.  O kan Josẹfu paapaa, idanwo si de ba a nigba ti gbogbo nnkan n lọ deedee fun un.

Gẹgẹ bi ẹni ti o ri oju rere ni ile ọgá rẹ̀, ojuṣe Josẹfu ni lati ri i pe a ṣe itọju gbogbo ohun ini ọkunrin ọlọrọ yii. Awọn iṣẹ́ rẹ̀ mu un sunmọ aya oluwa rẹ̀, nitori oun jẹ́ arẹwa ọkunrin, aya oluwa rẹ̀ n wá ọna lati tàn an jẹ ati lati fa a lọ sinu ẹ̀ṣẹ. Ni titẹ̀ si ifẹ ọkàn ati imọran obinrin yii, Josẹfu yoo já Ọlọrun ati oluwa rẹ̀ tilẹ̀. O bẹ̀ru Ọlọrun, o si fẹ Ẹ, kò si fẹ ṣe ohun kan ti yoo mu Un binú. O si ni ọkàn imoore si oluwa rẹ̀, Pọtifari pẹlu, ẹni ti o rà a lẹru tẹlẹ ri, ṣugbọn ti o si ti fi oju rere hàn fun un, ti o si ni igbẹkẹle ninu rẹ̀ lati igba naa wa.

Awọn idanwo kan wa ti a gbọdọ fi ọkàn akin pade, ti a ni lati doju kọ, ki a si bori rẹ̀, ṣugbọn awọn miiran wà ti a gbọdọ sá fun. Ni iru ọran bayii, bi a bá duro lati jiyan tabi gbà a yẹwo, ibi yoo de ba wa. Itọni ti o dara lati tẹle ni, “Dojuja kọ ohunkohun ti o fara jọ ẹṣẹ.” Iwa Josẹfu kún fun ẹkọ gidigidi. Kò bá ara ati ẹ̀jẹ̀ gbimọ pọ̀, nitori o mọ pe Egipti jẹ́ orilẹ-ede abọriṣa, nibi ti ẹ̀ṣẹ ti o buru ju lọ gbé gbilẹ, iranwọ kiranwọ ti o ba ri gba yoo jẹ́ otubantẹ.

O jinna réré si akoso ati itọni abẹ́ ile rẹ̀. Ọpọlọpọ eniyan ti o wà ni iru ipo bayii ti rò pe wọn ni lati “tẹle ọpọ eniyan” ki wọn si “tẹ̀ si ibi ti ayé tẹ̀ si.” Ṣugbọn ọkunrin ẹni iwa-bi-Ọlọrun yii kò ṣe bẹẹ. Ifọkansin rẹ̀ kò duro lori pe o wà lori oke tabi pẹtẹlẹ. O gba Ọlọrun gbọ́, Ẹni ti I ṣe Onidajọ ti ó wà laaye titi, ti o daju pe O maa n jẹ ẹni ti o ba rú ofin Rẹ̀ niya, ṣugbọn Oun jẹ́ Ọlọrun ifẹ pẹlu, ti o mura tán lati fi ère fun awọn iranṣẹ Rẹ̀ oloootọ. O ṣetan lati sin Ọlọrun yii ni ibi gbogbo ati ninu ohunkohun ti o wù ki o dé. Ohun ti o le ṣe ni Kenaani gan an ni o ṣe ni Egipti.

Aṣà Satani ni lati kọ́ tan eniyan jẹ lati dẹ́ṣẹ̀, lẹyin naa bi ẹ̀tan naa kò ba bọ́ si i, yoo fi oluwa rẹ̀ sùn pe o ti dá ẹ̀ṣẹ naa gan an. Oun ni “olufisun” awọn arakunrin. Aya Pọtifari dán Josẹfu wò; nigba ti o ri i pe oun kuna, o fi i sùn pe o ti ṣe ibi naa ti i ba ti i si lati ṣe. O gba ọna yii lati gbẹsan lara Josẹfu ati lati bọ́ lọwọ itiju ti i ba de ba a pẹlu. Olukuluku wa ni eṣu ti fi sùn pe o ti ṣe ohun ti kò tọ́, nigba ti o jẹ pe irọ́ ni o n pa lati fi mu wa, ki o si jẹ ki a ṣiyemeji iṣẹ oore-ọfẹ ti Ọlọrun ti ṣe ni ọkàn wa. Ni irú ipo bayii a kò gbọdọ bá eṣu tayo. Nigba yii ni a gbọdọ dojuja kọ ọ pẹlu gbogbo agbara ti Ọlọrun ti fi fun wa, ki a si sá fun irú idanwo ati ifisùn ti o le rán ni lọ si iparun. Bi a bá gba ọ̀na miiran, a o bì wa ṣubu.

Akoko idanwo, iyiiriwo ati ẹ̀kọ́ ti o le ju lọ ni igbesi-ayé Josẹfu bẹ̀rẹ nihin. Tità ti a tà a si oko-ẹrú, gẹgẹ bi ẹrú jẹ́ idanwo ti o wúwo fun igbẹkẹle ti o ni ninu Ọlọrun Olodumare bi Olupamọ awọn ti Rẹ̀. Ṣugbọn nisisiyii, idanwo rẹ̀ tubọ wá ga si i, nitori a fi i sinu tubu lori ẹ̀sùn èké, nigba ti o jẹ pe bi o ba lọ ṣubu sinu ẹ̀ṣẹ naa ti o si gbagbe Ọlọrun ati ofin pẹlu ẹ̀kọ́ Rẹ̀, oun iba bọ́ kuro ninu ijiya yii. Ṣugbọn ọpẹ ni fun Ọlọrun pe Josẹfu ṣe oloootọ́ si Ọlọrun, o si fi hàn pe oun ṣe e gbẹkẹle ni ipò giga ninu eto Ọlọrun fun igba ti n bọ̀.

Ẹni kan ti sọ bayii pe, “Awọn ẹyẹ wọnni ti a ti fi ọwọ́ lile tọ́ ni i fo lọ si ibi giga jù lọ.” Ọlọrun maa n mu awọn iranṣẹ Rẹ̀ la ọpọ iyiiriwo kọja, ki a ba le yọ́ gbogbo ìdàrọ́ ara wọn kuro patapata, ati ki wọn ba a le kọ́ bi a ti i ni igbẹkẹle ti o le ninu Ọlọrun nikan ṣoṣo pẹlu fun ohun gbogbo ni ayé.

Eso iwa rere Josẹfu ninu tubu ni igbẹkẹle ati ifọkàntan miiran ti onitubu tun fun un. Ohun ti o kẹyin gbogbo rẹ̀ ni pe o di alaṣẹ ilẹ Egipti, o si ri oju rere Ọlọrun ti o tobi ni Ọrun ati ni ayé.

## AWỌN IBEERE

1 Ta ni o ra Josẹfu nigba ti awọn ará Iṣmaẹli ta a bi ẹrú?
2 Iru iṣẹ-iranṣẹ wo ni Josẹfu ṣe fun ọgá rẹ titun?
3 Ki ni Ọlọrun yoo ṣe fun awọn wọnni ti o fi oju rere hàn fun awọn eniyan Rẹ̀ ti o si sure fun wọn?
4 Bawo ni Josẹfu ti dagba tó lakoko yii?
5 Njẹ Josẹfu tun ni anfaani oju rere ti o ni pẹlu ọgá rẹ̀ ni akọkọ sibẹ?
6 Iru iha wo ni a ni lati kọ si iyiiriwo ti o bá de ba wa, paapaa eyi ti a jiya rẹ̀ lai nidi?
7 Njẹ fifi Josẹfu sinu tubu lai tọ́ yii fi ikorò sinu ọkàn rẹ̀ si Ọlọrun?
8 Njẹ ọga Josẹfu ha ti mọ̀ nnkan nipa Ọlọrun Abrahamu ati ti Isaaki rí?
9 Ki ni ṣe ti owe yii, “Nigbati o ba wà ni Romu, ṣe bi awọn ará Romu ti n ṣe” jẹ́ owe ti kò dara lati tẹle?
10 Sọ awọn ẹ̀kọ́ ti o jẹ mọ́ igbesi-ayé Onigbagbọ́ nipa iwa ati iṣe ti o ri kọ́ ninu ẹ̀kọ́ yii?